AUG 1965


# IROHIN IMỌLẸ

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 1,419 TUESDAY AUGUST 3, 1965 (2D)


## Egbẹ UPGA Fẹ Ṣe Ipade Lori Ibo Eko

EKO:— Ninu irohin kan to de ọwọ wa ni a ti gbọ pe awọn olori ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) ni ilu Eko yio ṣe ipade kan lori eto idibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko ti nwọn yio ṣe idibo rẹ ni ọjọ kẹdogun oṣu kẹwa ọdun yi.

Irohin na tun fi ye wa pe ninu ipade ti awọn olori ẹgbẹ UPGA ti ilu Eko yio ṣe yi ni nwọn yio ti ṣe eto lori idibo si ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu Eko ati pe awọn Olori ẹgbẹ na tun jiroro lori bi nwọn yio ti ṣe mu awọn enia ti nwọn yio di ito fun ni gbogbo aye ijoko mejilelogoji ti nwọn yio ṣe idibo si.

Ninu ipade ti awọn olori ẹgbẹ UPGA ni ilu Eko ba ṣe na ni nwọn yio fi abayọri eto ipade na ranṣẹ si awọn Aṣiwaju ẹgbẹ UPGA mejeji Dọkita M. I. Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ati Adele Aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S. Adegbenro lati ṣe eto le lori.

Onirohin wa kan ran wa leti pe ni ọdun 1962 ni awọn enia ilu Eko dibo lati yan awọn enia mejilelogoji ti o lọ ṣe Aṣoju wọn ni ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu Eko lasiko na.

# EGBẸ UPGA NI YIO WỌLE NINU IBO TI MBỌ YI

OSHODI:- Gbogbo ilu Oshodi lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun awọn enia ti nwọn to ẹgbẹta (600) to wa sibi ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti iha Gusu Ikẹja ṣe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi nigbati Alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre fun Mushin ati agbegbe rẹ ti iṣe iha Gusu Ikẹja nba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ lori eto idibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi.

Ninu ọrọ Alaga ẹgbẹ na, Ọgbẹni Adeyiga Akinsanya kesi awọn Obinrin Ọlọja lati lọ mura silẹ ati pe ibo ti nwọn lo ṣe pataki ju ninu idibo to mbọ yi.

O tun kilọ fun awọn Ọkunrin ati paapa julọ ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre lati lọ mura nipa ti idibo to mbọ yi. O ni ki nwọn si duro gbọin gbọn ti apoti idibo ti nwọn ba ti di ibo tan ati pe ki nwọn maṣe gba ẹgbẹ Dẹmọ laye lati lu jibiti ninu idibo na.

Ọgbẹni Akinsanya tun kilọ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na lati mu iwa oju ko koro kuro lọkan ki nwọn maṣe ta ogun ibi wọn fun ẹgbẹ ọdalẹ ninu idibo to mọọ yi

O ni asiko ti to b a y i lati pa ẹgbẹ Dẹmọ run patapata ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati wipe ohunti o le pa ẹgbẹ na run ni ipinlẹ yi ni ọna bi nwọn yio ti ṣe kọ gbogbo awọn ti nwọn ba ti mu silẹ lasiko ibo k i nwọn fi tọkantọkan dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ninu idibo to mbo yi,

Ọgbẹni Akinsanya t u n se alaye fun awọn enia na lati lọ wo oke iṣoro to wa fun gbogbo enia ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati igbati ẹgbẹ Dẹmọ ti fi ọna e r u gba akoso ipinlẹ na O ni ti nwọn ko ba fẹ ṣe asiṣẹ ninu ibo yi o ni ki enikẹni maṣe dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ.

Siwaji si i ọgbẹni Akinsanya tun ṣe alaye pe ohunti ẹgbẹ Afẹnifẹre nja f u n bayi ni eto ilọsiwaju awọn mekannu ati pe ohunti ko ni mu awọn ọmọ to m b ọ lẹhin ri wahala kankan ninu ohunti nwọn ba da wọle.

O tun rọ awọn enia na lati lọ ni suru ati p e ki nwọn maṣe k ọ l u ẹnikẹni ninu idibo to mbọ y i tabi pe ki nwọn lọ ma ba ẹniti ko ba bu wọn Ọgbẹni Akinsanya tun rọ awọn enia ilu Oshodi, Ikeja Shogunlọ ati ilu yoku lati ri p e nwọn dibo to mbọ yi f u n ẹgbẹ UPGA.

O tun ṣẹlalaye lori iwa buburu ti ẹgbẹ Dẹmọ ma a nhu eyiti o ṣe alaye pe bẹ na ni nwọn ṣe lasiko

WO OJU EWE KẸFA

## Ijọba Ti Bẹrẹsi Tun Oju Ona Mushin Se




MUSHIN:- Lati ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ ki ni oṣu yi ni awọn osi sẹ Apapọ Ijọba ti bẹrẹsi tun oju titi Mushin ṣe ni gbogbo ibiti oju ọna na ti bajẹ ti awon moto ko si le gba ibẹ mọ

Aworan Oke yi ni diẹ ninu awon osiṣẹ na ti nwon ntun ọna na ṣe

Gbogbo awon moto ni nwon ko tun le gba oju ona Mushin na lo si Agege mo, ṣugbon oju ona Ikorodu ni awon moto ngba lo si Agege nisisiyi

Ninu Irohin to jade lati ile iṣẹ Minista Ala Imojuto igbokegbodo ọkọ ati iṣẹ fun apapọ Ijọba Naijiria fi ye wa pe odidi ọsẹ mẹrin ni nwọn yio fi tun oju ọna na ṣe ki o to di pe yio ṣe ri i daada fun awọn onimọto

# Idi Rẹ Ti Ọsanyin Ṣe Di Ẹlẹṣẹ Kan

LATI ỌWỌ ARABA, EKO

Iki ti a ki mi, ko jọ ti ẹniti o mọ ore
Iwo ti a nwo mi, ko jọ ti ẹniti o mọ
igbehin ọrọ ti ko sunwọn,
Bi enia ba ndun ọrọ li adunju
Ko ni ri ẹni ba ṣire mọ
A difa fun Ọrunmila lọjọ ti Ọsanyin
nba ṣọrẹ pọ. Ọbara-kobodi

Li ọjọ na lọhun Ọsanyin ko ri ṣe mọ o wa kerahun lọ ba Ọrunmila ninu ile, o wi fun pe, lati bi iwọn ọjọ mẹta sẹhin, on ko ri eru jẹ, on ko ri ṣe rara, Ọrunmila gbọ Iporun rẹ, o jan mọlẹ, o wa bẹrẹsi ki i bayi wipe

Olumọ mọ, a ko gbọ poroporo odo.
Ọganjọ gan dundun a ko gbọ girigiri ẹsẹ.
Afaimọ, ki awo ma sun ninu ebi-Afaimẹ.

Ọrunmila wifun Ọsanyin pe, on ti mura lati lọ si ajo nitori na on fẹ ki Ọsanyin ba on kọlọ si irin ajo na boya nwọn le ri eru jẹ Ọsanyin gbọ. o mura o si ba Ọrunmila lọ si ajọ na. Nwọn de ilu Ilara, nwọn jeru jeru, nwọn de Ijero, nwọn de Ila-ọrogun, nwọn de ọdọ lọba-lọba, awọn de ọdọ Ọlọja mẹrẹrindinlogun, nwọn de ọdọ Erinkinriok'n, nwọn jeru lọdọ gbogbo wọn, ṣugbọn awọn ọba nwọnyi se ileri wipe awọn yio san ẹjẹ wọn nigbati nwọn ba nọọ ni irin.

Nigbati o to iwon oṣu meta lori irin ajo na, Ọrunmila pe Ọsanyin wipe eyiti nwọn rin ninu irin ajo yi to, ki o jẹki nwọn lọ gba ẹjẹ ti nwọn jẹ fun wọn ki nwọn si ma lọ sile. Osanyin dahun, o wipe howu! eyini ma yak'a-kin iu, ki Ọrunmila jẹki o lo bi iwọn oṣu kan lẹhin na, Ọrunmila si gba bẹ

Ni ọjọ keji, Ọsanyin da gbere fun Ọrunmila wipe, on fẹ lọ kesi aburo Iya on kan ti o mbe ni ilu keji, Ọrunmila dahun pe, o dara ki o maṣe pẹ. Bayi ni orisa Ọsanyin ba gba ona ehin ọ gba gbogbo ẹjẹ ti nwọn tijẹ fun wọn tan, o si kori ilu tirẹ, Ọrunmila reti ed, o remu-remu, nigbati ko ri Ọsanyin ki o pada wa ba ou, o'pada lori irin ajo rẹ sile, o ya lati gba awọn ẹjẹ ti awọn ti ṣeleri fun wọn, kakiri ni bi gbogbo ti o ba de, nwọn o sọfun pe, ọmọ awo rẹ ti wa gba ẹjẹ lo

Gẹrẹ ti Ọsanyin ko gbogbo eru nwọnyi dele, ni ẹse rẹ kan ba bẹrẹsi jera, Ni ọjọ keji ti Ọrunmila dele o lọ kesi Ọsanyin, Nigbati Osanyin ri ... paa, o wa bẹẹ wipe ki o gba on nipa ẹsẹ na, Ọrunmila tun jan Iporun rẹ ... Nigbati odu Ọbara ko bodi ti a ki si oke ... yi yọ, o dahun wipe Bi a ba wipe ki Ọsanyin ma ku were were, eru goke, bi a wipe ki o ma ku wara wara ohun gbogbo di meji meji, Nigbati Ọsanyin ko ti gbo bo eru na ko da silẹ tan ni ẹsẹ rẹ kan ba fi ta baje, ti o si sọ Ọsanyin di elese kan. Ẹkọ inu rẹ ni wipe, Bi a ba ṣore fun ẹni kan ti o ... kesi mọọ, maṣe jẹki inu rẹ bajẹ nitori rẹ bi o ti wu ki o pẹ to ẹsan mbọ wa ko lori alaimote,

## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20-Feb 18) Ọjọ oni ko ni ri fun ọ bi o ti lero, awọn enia kan yio si maa pẹgan rẹ gbiyanju lati ri awọn ọrẹ rẹ loni ki o si gba imọran.

PISCES (Feb19-March) O ṣe alabapade awọn enia kan ti yio ṣe iranlọwọ fun ọ loni.

ARIES (Mar 21 April 19) Ọjọ oni dara fun ọ O si ba awọn enia kan dada ti nwọn yio ba ọ da imọran fun ọjọ ọla.

TAURUS (April 21 May 20) Awọn nkan yio jẹ ini ra diẹ fun ọ loni, ti o ba si ṣe wọn idiwọ diẹ le wa fun ọ Maṣe ba inu jẹ, ọjọ ọla yio dara

GEMINI (May 21 June 21) Jẹki gbogbo nkan ti o ba nṣe loni o tẹ ọ lọrun, ki o ṣọra pẹlu ọrọ ibinu ati owu jijẹ.

CANCER (June 22 July 22) Ọjọ oni dara fun ọ la ti ṣe ibẹwo awọn enia jankanjankan ti o ba si fi ọran rẹ lo wọn nwọn o ṣe iranlọwọ fun ọ.

LEO (July 23 Aug 22) Gbogbo ohun ti o ba ri loni ni ki o fi tayọtayọ gba ki o si jẹki o tẹ o lọrun, Ṣọra pẹlu ọrọ ibinu

VIRGO (Aug 23 Sept 22) Ọjọ oni dara fun ọ lati sunmọ awọn enia ti o yi ọ ka, ki o si ba wọn ṣe idapọ ti tun.

LIBRA (Sept 23 Oct23) Maṣe jafara si ohun gbogbo ti o nṣe loni, ki o si ma a ranti ẹbinọla igba ki i lọ bi orere, aiye kii to lọ bi ọpa ibọn.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Bi o tilẹ jẹ pe ọjọ oni dara fun ọ, sibẹ ohun ibanujẹ kan ti ko ni mu inu rẹ dun wa niwaju rẹ. Kọ lẹta si awọn ọrẹ rẹ loni.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Awọn enia oninure ni iwo o ba sọrọ loni ṣọra lati ma a ṣe akiyesi ọrọ ti o ma a jade lẹnu rẹ si wọn. Ẹyin lohun, ti o ba bọ ko ṣee ko.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 19) Orire wa fun ọ loni, ninu ohun gbogbo paapajulọ lọdọ olufẹ rẹ. Awọn na yio maa woju rẹ fun iranlọwọ loni,


## EGBOGI JEDIJEDI



CYCLOVEN

Aworan egbẹ yi fi han gba ngba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọlẹ ... oigbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi eniti ibiti nma ngba ise igbọnsẹ; Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si ṣoro papo lati ṣe iwosan rẹtan patapata.

Ọpolopo egbogi li o wa tita nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma npolowo awọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ni a le ri mewa ninu awọn ogun to le ṣe iwosan arun na daradara.

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si ile iwosan lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin odun diẹ ... rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orişirisi Jẹdijẹdi ni o ... ti o bẹrẹ aiko maṣe ... nsẹ deede tabi ... kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹlomiran ... oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu ... ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnṣẹ tabi ... omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣe wa idi rẹ ki o si da ... daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi pat pata ... ro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14,. Wakeman Street, Yaba

# SHOYINKA TUN GBE DE!

Fun isegun Aiye ati awon abatenije ra

## Turari Isegun Agba

10s 6d pangolo 2s 6d paketi



J. O. Shoyinka

Fun Iwosangidi ati ibolowo aiye, biku, aita oja ra

## *Iwe ilana ifa yanrin tite ati etutu sise 20s

Fun Isegun ota ile, ode, awon Agba ati adura Ajebidan ra

# IWEAFOSE

Isedale Yoruba ati

# PSALM

Ajebidan 3s 6d pere

*Fun itumo ijinle ala ati iwadi nkan nipa ona 'IFA' pelu ogun Ajebidan lati owo Josefu Alala ra*

## Iwe Itumo Ala (Josefu Alala)

*3s eyo 25s dosin.*

*anta awon orisirisi iwe Egbogi miran bi*

*Iwe Egbogi Awogba Arun 20s*

AKIYESI: ENIKENI TI O BA RA NINU IWE YI YIO GBA PAKETI TURARI ADURA LOFE,

**SHOYINKA** 9, Iyalla Street, Mushin.

